# ÌTÀN ÌJÌNLẸ̀ NÍPA ÌSỌTẸLẸ

## OHÙN ẸNI TO NKÍGBE NÍ AGINJÙ

## Ìtàn ...

**Matteu 3:1-12**

Jesu wípé, "Ninu awọn ti a bí ninu obinrin, kò sí ẹniti o ti idide jù Johannu Baptisti lọ." Matteu ẹ̀ẹ̀:ẹ̀ẹ̀. Kinni a mọ̀ nipa ọkunrin to n da nikan gbé yi, ẹniti Jesu pè ni ẹni to tobi jù ninu awọn woli?

Nígbàtí Johannu bẹ̀rẹ̀ si iwaasu ni ijù ti Judea, awọn ènìyàn wá lati maili ti o yi ká lati wá gbọ́ ọ̀rọ̀ agbara, lai bẹ̀rù, ti o si kún fun ìrẹ̀lẹ̀. Ni idakeji si awọn olori ẹ̀sìn ni ìgbà naa, ayé Johannu kún fun ìwà mímọ́ ati ìwà pẹ̀lẹ̀. Nigbati awọn alufa nwọ aṣọ olowo iyebiye, Johannu nwọ aṣọ ìwọ̀ntunwọnsi ti irun ibakasiẹ pẹlu àmùrè alawọ fun ìgbànu. Nigbati wọn nṣe ayẹyẹ, Johannu ngbawẹ tabi ki o ma jẹ eeṣú (Ẹarob pods) ati oyin ìgàn. Ó kọ̀ lati mu ọti-waini tabi ọtí-lile, ki o le kun fun Ẹmí Ọlọrun (Luku 1:15). Dípò sinagọgu nlá to lẹwa, Johannu yan ibi omi ati ibi apata gẹ́gẹ́ bi ile iwaasu rẹ̀. Laipẹ́ awọn eniyàn nbèèrè pé, "Njẹ́ ọkunrin yi le jẹ́ Elijah bí?"



©Pacific Press

Johannu ma nmura bi awọn woli inu Majẹmu Lailai, ṣùgbọ́n ki iṣe Elijah to pada wayé. Angẹli Gabrieli ti ṣe àlàyé fun awọn obi Johannu ki a to bi i, pé "Ẹmí ati agbara Eliasi (Elijah ni èdè Giriki) ni oun o si fi ṣaaju... ki o le pèsè eniyàn ti o mura silẹ dè Oluwa." Luku 1:17.

Kọ́kọ́rọ́ iṣẹ iranṣẹ Johannu ni pé yio lo agbara kanna ti iṣe ti Ẹmí Mímọ́ bi iti Elijah lati mu ki isọjí wà laarin awọn ènìyàn Ọlọrun. Iṣẹ́ rẹ̀ ni lati waasu ironupiwadà ẹ̀ṣẹ̀ ati lati pèsè awọn eniyàn silẹ̀ fun wíwá Jesu ni àkọ́kọ́.

Bibeli sọ pe ni akókò ikẹhin pe awọn ogun ti Elijah ati ti Johannu Baptisti yio dide lati se iru iṣẹ pípèsè ayé silẹ fun ipada wá Jesu ni ìgbà keji. "Wò ó, emi o rán woli Elijah si nyin, ki ọjọ́ nla-nlà OLUWA, ati ọjọ ti o li ẹru to de." Malaki 4:5. (Tún wo Joeli 2:28-31).

# Ẹ̀kọ́

Dí àwọn àlàfo wọ̀nyí, lẹ́hìn tí o bá ti kà ẹsẹ Bibeli kọ̀ọkan tán.

1. Kinni asiri ìgbé-ayé ẹni Ẹmí Johannu?

**Luku 3:16**
Johannu dahun o si wi fun gbogbo wọn pe, Lootọ li emi nfi omi baptisi nyin: ṣùgbọn ẹniti o lágbára ju mi lọ mbọ̀, okùn bàtà ẹsẹ ẹniti emi ko __________ itú: oun ni yio fi Ẹmi Mímọ́ ati iná baptisi nyin.
**Johannu 3:30**
Oun kò le ṣaima pọsi i, ṣugbọn emi kò le saima __________ .

Àkíyèsí: Ìgbé-ayé ẹni Ẹmi Johannu Baptisti hàn pẹlu ìwà ìrẹ̀lẹ̀ ti kò lẹ́gbẹ́. Ìbaṣepọ̀ to lọ tààrà wà laarin iṣẹ́ iranṣẹ Johannu to lagbara ati ti yiyọnda ara ẹni pátápátá ti Johannu ní sí Oluwa wa. O jẹ ayọ̀ Johannu to ga jù lati ma a tọka awọn ẹlomiran si Jesu ju lati ma tọka si ara rẹ lọ. Ohun gbogbo ti Johannu se ni a ṣe lati mu ògo ba orukọ Ọlọrun.

2. Njẹ́ Johannu Baptisti ka iwé mímọ́ bí?

**Johannu 1:23**
O wípé, Emi li __________ ẹni ti nkigbe ni ijù, Ẹ ṣe ki ọ̀nà Oluwa tọ́, gẹgẹ bi __________ Isaiah ti wí.

Àkíyèsí: Bẹ̀ẹ̀ni! Johannu yọ ẹsẹ Bibeli yi lati inu Majẹmu Lailai lati fi se ẹ̀rí pe o ni ìpìlẹ̀ rere ninu Iwé Mímọ́. Bibeli tun sọ fun wa pé Johannu kọ́ awọn ọmọ ẹhin rẹ pé ki wọn ki o ma gbàwẹ̀ ki wọn si ma a gbadura nígbà gbogbo (Matteu 9:14). Èyí tún jẹ́ ẹ̀rí ìfẹ́ ìjìnlẹ̀ ti Johannu ní sí Oluwa. Li ọ̀nà kannan, nipaṣẹ̀ adura ati Bibeli kíkà funrara wa, a le mọ Ọlọrun ki a si tún fẹ́ràn Rẹ ati ki a sì tún gba Ẹmí Mímọ́.

3. Njẹ́ Johannu Baptisti fẹ́ lati jẹri fún Jesu bí?

**Johannu 1:29**
Ni ijọ keji Johannu __________ Jesu mbọ̀ wá sọdọ rẹ̀; o wipe, __________ o, Ọdọ Agutan Ọlọrun, ẹniti o kó ẹ̀ṣẹ̀ ayé lọ.

Àkíyèsí: Nípa ẹ̀dá, Johannu jẹ ẹni to ma ndá nìkan gbé (Luku 1:80). Síbẹ̀ o tún fẹ́ laika ẹ̀gàn ati ẹ̀mí ara rẹ̀ sí lori pe o ntọ́ka si Jesu bi Olugbàlà araye fun awọn ènìyàn. Bakanna, awọn ti o fẹ́ Oluwa loni, yio yàn lati pa ìbẹ̀rù ti ati pe wọn ko ni wo bi ko se rọrùn lati jẹri fun Jesu.

4. Njẹ́ iwaasu Johannu ti o ṣe tààrà jẹ́ ìtẹwọgbà ní aarin awọn olori ìlú ati awọn olori ẹ̀sìn bí?

**Luku 7:30**
Ṣùgbọ́n awọn Farisi ati awọn amofin __________ ìmọ̀ Ọlọrun fun ara wọn, a kò baptisi wọn lọ́dọ̀ rẹ̀.
**Luku 3:19,20**
Ṣùgbọ́n Herodu tetraki, ti o bawi nitori Herodia aya Filipi arakunrin rẹ̀ ati nitori ohun buburu gbogbo ti Herodu ti ṣe, O fi eyi pari gbogbo rẹ̀, niti o fi Johannu sinu tubu.

Àkíyèsí: Johannu sọ̀rọ̀ gbangba lori ẹ̀ṣẹ̀ to gbajúmọ̀ laarin awọn ènìyàn, ti àwọn olórí ẹ̀sìn gan sì gbádùn lati má a dá. Ọ̀rọ̀ ironuọ piwada ati ìwà mímọ́ ti Ọlọrun ni ikẹhin ọjọ́ yio jẹ́ èyí ti kò gbajúmọ̀ laarin awọn olori ìlú ati laarin awọn olori ẹ̀sìn, ṣùgbọ́n yio dúró lori Bibeli.

5. Ṣe Bibeli lòdì si wúrà ati awọn aṣọ olówó iyebíye ní wíwọ̀?

**1 Timoteu 2:9**
Bẹ́ẹ̀ gẹgẹ ki awọn obinrin ki o fi aṣọ __________ ṣe ara wọn li ọṣọ́, pẹlu itiju ati ìwà airekọja; kì iṣe pẹlu irun dídì ati __________ , tabi pearli, tabi aṣọ olowo iyebiye.
**1 Peteru 3:3**
Ọ̀ṣọ́ ẹniti ki o má jẹ ọ̀ṣọ́ __________ , ti irun didi, ati ti wura , tabi ti aṣọ wíwọ̀.
**Isaiah 3:18-21**
Li ọjọ́ naa Oluwa yio mu ogo ṣaworo wọn kuro, ati awọn ọṣọ́ wọn, ati iweri wọn bi oṣupa, Ati ẹ̀wọn, ati __________ , ati ìbòjú, Ati àkẹtẹ̀, ati ohun ọ̀ṣọ́-ẹsẹ, ati ọjá-ori, ati ago oloorùn didùn, ati oruka eti, __________ , ati ọ̀ṣọ́-imu.

Àkíyèsí: Bẹ̀ẹ̀ni! Johannu wọ aṣọ olówó kékeré, ti iṣe aṣọ ìwọ̀nọ́ tunwọ̀nsí - apẹẹrẹ rere fún awọn Kristiani lati tẹ̀lé. Afẹ́ẹ yẹyẹ ati awọn oge to nfa ìfẹ́kufẹ lode oni lo npè fun idanwò nla ati jijẹ gbẹ̀ṣẹ̀. Ọlọrun kò fẹ́ ki a ma wọ aṣọ bi àpò, síbẹ̀, aṣọ olówó geọ́ gere, to ntàn yinrin kò gbọdọ̀ wà ninu apoti aṣọ kristiani. Bi o tilẹ̀ jẹ́ wípé wíwọ wúrà jẹ ohun to ṣe ìtẹ́wọ́gbà ni gbogbo ayé, o ni àwòrán buruku ninu Iwé Mímọ́. O le ma mọ gbogbo ohun ti a daọ́ rukọ ninu Isaiah 3:18-23 tán, ṣùgbọ́n awọn ènìyàn ni apá ibikan ninu ayé mọ̀ wọ́n. Pípọ̀ ninu awọn ọ̀ṣọ́ pagani ni o ti nfarahàn ninu àṣà awọn ara ìwọ̀ oorùn bayi.

6. Njẹ ibaṣepọ̀ wà laarin ikun fun Ẹ̀mí Mímọ́ Johannu ati ounjẹ ti o jẹ?

**Luku 1:15**
Nitori oun o pọ̀ niwaju Oluwa, kì yio si mu __________ , bẹ́ẹ̀ni kì yio si mu ọti-lile; yio si kún fun __________ àni lati inu iya rẹ̀ wá.

Àkíyèsí: Awọn Kristiani gbọ́dọ̀ sá fun ọti lile pátápátá, kí wọn le pa ọkàn wọn mọ́, ki wọn sì le gbọ́ ohùn Ẹmí Ọlọrun (Owe 23:31;32; Habakkuku 2:15; 1 Peteru 5:8).

7. Kinni idi ti ohun ti a njẹ tabi ti a nmu fi kan Ọlọrun?

**Onidajọ 13:7**
Ṣugbọn oun sọ fun mi pe, Kiyesi i, iwọ o lóyún, iwọ o si bi ọmọkunrin kan; nitori naa má ṣe mu ọti-waini tabi __________ , bẹ́ẹ̀ni ki o má ṣe jẹ ohun àimọ́ kan: nitori Nasiri Ọlọrun li ọmọ naa o jẹ lati inu wá titi di ọjọ́ ikú rẹ̀.
**1 Korinti 6:19**
Tabi, ẹnyin kò mọ̀ pe __________ nyin ni __________ Ẹmi Mímọ́ __________ , ti mbẹ ninu nyin, ti ẹnyin ti gbà lọwọ Ọlọrun? Ẹnyin ki si iṣe ti ara nyin?

Àkíyèsí: Ìbáṣepọ̀ to lọ tààrà wà laarin ounjẹ ti a njẹ ati ohun ti a nmu ati bí ọpọlọ wa ṣe nsiṣẹ́, agbára lati bori idanwò ati okun lati fi ìyàtọ̀ laarin rere ati búbúru hàn. Ohunkohun ti Kristiani ba nṣe - ti ó fi kanra ohun jíjẹ ati mimu - ni a gbọdọ̀ ṣe lati yin Ọlọrun logo (1 Korinti 10:31).

8. Kinni Bibeli sọ nipa ìhùwàsí ayé?

**Jakọbu 4:4**
Ẹnyin panṣaga ọkunrin, ati panṣaga obinrin, ẹ kò mọ̀ pé ìbárẹ́ ayé ìṣọ̀tá Ọlọrun ni? nitori naa ẹnikẹni ti o ba fẹ lati jẹ ______ ayé di __________ Ọlọrun.
**2 Korinti 6:17**
Nitori naa ẹ jade kuro laarin wọn, ki ẹ si yà ara nyin si __________ , li Oluwa wi, ki ẹ máṣe fi ọwọ́ kàn ohun aimọ́; emi o si gbà nyin.







YOR-SP21.indd 1
12/14/12 9:18 AM

**1 Johannu 2:15**
Ẹ máṣe fẹran ayé, tabi ohun ti mbẹ ninu ayé. Bi ẹnikẹni ba fẹran ______, ifẹ ti Baba ______ si ninu rẹ.
**Romu 12:2**
Ki ẹ má si da ara nyin pọ̀ mọ́ ______ yi: ṣugbọ́n ki ẹ parada lati di ______ ni ìrò-inu nyin, ki ẹnyin ki o le ri idi ìfẹ́ Ọlọrun, ti o dára, ti o si ṣe ìtẹwọ́gbà, ti o si pé.

Àkíyèsí: Oluwa npe awọn ènìyàn Rẹ̀ loni lati gbé igbe ayé ti ó ní apẹrẹ lati ran awọn ẹlomiran lọ́wọ́, kí wọn le mura silẹ̀ de ìpadabọ̀ Jesu lẹ̀ẹkeji.

9. Kíló yẹ fún Kristiani lati yàn lati má a ronú le lórí?
**Filippi 4:8**
Li akotan, ará, ohunkohun ti iṣe ______, ohunkohun ti iṣe ọ̀wọ̀, ohunkohun ti iṣe títọ́, ohunkohun ti iṣe _______, ohunkohun ti iṣe fifẹ, ohunkohun ti o ni irohin rere; bi ______ ______ kan ba wà, bi iyìn kan ba si wà, ẹ maa gbà nkan wọnyi rò.
**Orin Dafidi 101:3**
Ẹmi ______ yio gbé ohun buburu __________ mi: emi korira iṣẹ awọn ti o yapa, kì yio fi ara mọ mi.

Àkíyèsí: Johannu Babtisti pàṣẹ fun awọn eniyan ki wọn sá fun ìwà ipá (Luku 3:14). Fún àwa, ohun ti a gbọ́dọ̀ sá fún ni wiwo awọn ìwà ipá fun ìgbádùn ara wa. Jesu kọ wa pé ẹ̀ṣẹ̀ ibalopọ̀ ati ìwà ipá ma ndariyọ lati inú èrò ati iṣe wa (Matteu 5:22, 28). Nitori idi èyí, awọn Kristiani gbọdọ sá fun èrè inú amohun-maworan, eré ori-ìtàgé tabi ìwé ti o le mu wọn ma a ro èrò-kerò ninu ọkàn.

10. Irú orin wo ni awọn Kristiani otitọ́ ma nfẹ́ràn?
**Orin Dafidi 40:3**
O si fi ________ _________ si mi li ẹnu, ani orin iyin si Ọlọrun wa: ọ̀pọ̀ eniyàn ni yio ri i, ti yio si bẹ̀rù, ti yio si gbẹkẹle OLUWA.
**1 Samueli 16:23**
O si ṣe, nigbati ẹmi búburú lati ọdọ Ọlọrun wá ba de si Saulu, Dafidi a si fi ọwọ́ rẹ kọrin lara _________: a si _________ fun Saulu, ara rẹ̀ a si da; ẹmi buburu naa, a si fi i silẹ.

Àkíyèsí: Ò hàn gbangba pé púpọ̀ ninu awọn orin to gbòde ninu ayé ni kò ràn wá lọ́wọ́ nipa ti ẹ̀mí. Dipo ki o ràn wá lọwọ nípa ti ẹ̀mí, se ni o npa ìfẹ́ wa fun ohun ọrun run ti o si ma nfi agbara fún ara. Síbẹ̀, orin le e fún wa ní agbara nla lati ṣe rere. Nigbati ẹ̀mí buburu nyọ Ọba Saulu lẹnu, orin to njade lati ibi duru Dafidi yio si mu itura wa fun un ati pé yio tun le ẹ̀mí buburu naa lọ.

11. Ṣe ijó jíjó dara fun ìgbádùn Kristiani bí?
**1 Johannu 2:6**
Ẹniti o ba wipe oun ngbé inu rẹ̀, oun naa pẹlu si yẹ lati maa _______ gẹgẹ bi oun ti rìn.
**Titu 2:12**
O nkọ́ wa pe, ki a sẹ́ aiwa-bi-Ọlọrun ati ifẹkufẹ ______, ki a si maa wà li airekọja, li ododo, ati ni ________________ ni ayé isinsinyi.

Àkíyèsí: Ọ̀pọ̀ ninu awọn ijó ti o gbòde loni ni o ṣopọ̀ mọ orin ayé ti o si lagbara lori ìbálòpọ̀. Ninu ohun gbogbo a gbọ́dọ̀ ma bere wípé, "Kini Jesu fẹ́ ṣe? Mo rò pé Olugbàlà wa kò le pa ìdí tí Ó fi wáyé tì ki Ó sì má a jó àti si i gbé ẹṣẹ̀ sókè nítorí orin.



12. Njẹ́ Kristiani le ta tẹ́tẹ́ tabi gongo?
**1 Timoteu 6:10**
Nitori _______ ________ ni gbòngbò ohun búburú gbogbo; eyiti awọn miran nlepa ti a si mu wọn ṣako kuro ninu ìgbàgbọ́, nwọn si fi ________ púpọ̀ gun ara wọn li ọ̀kọ̀.
**2 Tessalonika 3:10**
Nitori nigbati awa tilẹ̀ wà pẹlu nyin, eyi li awa palaṣẹ fun nyin, pe bi ẹnikẹni kò ba fẹ ________, ki o maṣe jẹun.
**Owe 28:20**
Olootọ eniyàn yio pọ̀ fun ibukún: ṣugbọn ẹniti o ______ ati ______ kì yio ṣe alaijiya.

Àkíyèsí: Tẹ́tẹ́ le dabi igbati òògùn ti di bárakú fún ẹnikan. Ọ̀pọlọpọ lo ti ná owó ti wọn fi pamọ fun idile wọn ni inakuna ni ilé tẹ́tẹ́. Ọ̀pọ̀ "níọ̀rọ̀ ni kíákíá" ìpinnu ní o sopọ̀ pẹ̀lú ìjambá púpọ̀, owó iyebíye àti ìwà tó nmú ìbéèrè dání.

13. Kíló yẹ kí ò jẹ́ ìpinnu áwọn ènìyàn Ọlọrun loni?
**1 Johannu 3:22**
Ati ohunkohun ti awa ba bèrè, awa nri gbà lọdọ rẹ̀, nitori ti awa _______ ofin rẹ̀ mọ́, awa si nṣe nkan wọnni ti o ________ lójú rẹ̀.
**Oniwaasu 12:13**
Opin gbogbo ọ̀rọ̀ naa ti a gbọ́ ni pe: Bẹ̀rù Ọlọrun ki o si pa ofin rẹ̀ mọ́: nitori eyi ni fun ___________ eniyàn.

Àkíyèsí: Ẹnikan kò le e gbe ìgbé-ayé rẹ ni ọ̀nà to wù ú, ki o si wọ Ìjọba Ọlọrun ni opin ayé rẹ. Ní pàtó, idí ti Jesu fi wá si ayé - ni lati fi apẹrẹ ìgbé-ayé mímọ́ lélẹ̀ (1 Peteru 2:21).

14. Kilo ma mu kí ó rọrùn lati gbọràn sí Ọlọrun lẹnu lori gbogbo awọn ìgbé-ayé ti a ti mẹnubà ninu ẹ̀kọ́ yi?
**Johannu 14:15**
Bi ẹnyin ba ________ mi, ẹ ó pa ofin mi mọ́.
**1 Johannu 5:3**
Nitori eyi ni ifẹ Ọlọrun, pe ki awa ki o pa ofin rẹ̀ mọ́: _______ rẹ̀ ko si ________.
**Orin Dafidi 40:8**
Inu mi dùn lati ṣe ifẹ rẹ, Ọlọrun mi, nitootọ,_______ rẹ mbẹ li _______ mi.

15. Kíló dé ti igbé-ayé Kristiani fi jẹ́ ìpè gíga?
**1 Peteru 2:9**
Ṣùgbọ́n ẹnyin ni iran ti a ________, olu-alufa, orilẹ-èdè _______, eniyàn ọ̀tọ̀, ki ẹnyin ki o le fi ọla nla ẹniti o pè nyin jade kuro ninu okunkun sinu imọlẹ iyanu rẹ̀ ________.

Àkíyèsí: Gẹ́gẹ́ bi aṣojú Jesu, lotitọ Kristiani ni ìpè gíga! Johannu Baptisti ṣe ìrànlọ́wọ́ lati pèsè awọn èiyàn sílẹ̀ fún Jesu ni ìgbà ti Jesu kọ́kọ́ wá sí ayé, Ọlọrun ti pe awọn ènìyàn Rẹ̀ loni lati gbe igbé-ayé mímọ́ bí wọn ti nran awọn ènìyàn lọ́wọ́ lati pèsè wọn silẹ̀ fun ipadabọ Jesu lẹ́ẹ̀keji.



# Èsì Rẹ

Njẹ́ o ṣetan lati jẹ ẹni ọ̀tọ̀ "ohùn ẹni ti nkígbe ní aginjù" ati pé kí o jẹri nipaṣẹ igbe-ayé iwa bi Ọlọrun lati pèsè ẹlomiran silẹ fun ipadabọ Jesu lẹ́ẹ̀keji bí?

ÌDÁHÙN:_____________________

# Àfikún

Ipele yìí pèsè awọn irohìn afikún fun ikẹkọ síwajú si.

## Ikọ̀ tàbí Aṣojù Kristi

Bi ẹnikan ba di Kristiani, a ka irú ẹni bẹ́ẹ̀ mọ́ àwọn aṣojù lati inú ijọba tó dára. Bibeli sọ wipé, "Nitori naa awa ni ikọ̀ fun Kristi." 2 Korinti 5:20.

Iwé atumọ̀ èdè oyinbo tumọ ikọ̀ bi "ẹni to ni ìwé ẹ̀rí pẹ̀lú ipò tó ga jù ti a sì yàn lati jẹ́ asojú ilé lati ọwọ́ ijọba tàbí alaṣẹ kan, ti o le jẹ́ ìwọ̀n ìgbà díẹ̀."

Gẹ́gẹ́ bi ikọ̀ ṣe jẹ́ pàtàkì nipa ti ẹmí bẹ́ẹ̀ naa ni ikọ̀ jẹ́ pàtàki ninu ètò iṣeọ́ jọba. Ọmọ ijọba Ọlọrun kò da bi ọmọ ayé yi. A ti rán wa sinu ayé lati fi irú ẹni ti Jesu iṣe hàn ati bi O ti rí. Nipaṣẹ Ẹ̀mí Mímọ́ a di asojú Jesu - lati fi Jesu hàn ninu ohun gbogbo, bẹ̀rẹ̀ lati ibi ọ̀rọ̀ àti iṣẹ́ wa, àti ọ̀nà ti a ngbà jẹun, ati bi a ṣe nwọṣọ. Ni ọ̀rọ̀ miran, bi a ba ti di ọkan lara àwọn ẹni ijọba ẹmi ti Ọlọrun, a o ma gbe ìgbé-ayé lati fi ijọba ti a nsoju rẹ̀ hàn. Ninu 2 Korinti 3:18, Iwé Mímọ́ sọ wipé "gbogbo wa ... a npawadà sí àwòrán kan naa lati ogo de ogo,ani bi lati ọdọ Oluwa ti iṣe Ẹmi."

Awa ijọ, ni ọwọ́ ati ẹsẹ̀, ojú ati ẹnu, ati bẹ́ẹ̀ni, a tún jẹ́ etí fún Jesu ninu ayé loni. A jẹ́ ara Kristi (Efesu 1:22,23; 5:29,30; Kolosse 1:18). Saaju ki O to gòkè re ọrun, Jesu sọ fún wa pé, "Gẹ́gẹ́ bi Baba ti rán mi, bẹ́ẹ̀li emi si rán nyin." Johannu 20:21.

Gbogbo ìhà ayé wa lo yẹ ki o ma fi Jesu hàn, ki o si ma a fi ẹni ti Jesu jẹ́ hàn. "Ẹ jẹ́ ki imọlẹ nyin ki o mọlẹ tobẹ́ẹ̀ niwaju eniyàn, ki nwọn ki o le maa ri iṣẹ rere nyin, ki nwọn ki o le ma yin Baba nyin ti mbẹ li ọrun logo."

©2012 Ilé-iṣẹ́ Òtítọ́ Ìyanu
Àṣẹ ati Ẹ̀tọ́ lati tẹ ìwe yi jáde wa fún
Tí a tẹ̀ jade ní ìlú Amẹrika

AMAZING FACTS
P.O. Box 909
Roseville, CA 95678

YOR-SP21.indd 2
12/14/12 9:18 AM